# IBEERE ỌGỌTA

## Nipa Awọn Idajọ Nipa Ẹjẹ Osu ati Ibimọ




Lati ọwọ Ọlọlajulọ Ash-shaykh Ọlọpọlọpọ mimọ

**Muhammad Bn Sālihu Al-U'thaimeen**

Ki Ọlọhun ṣe aforijin fun un ati fun awọn obi rẹ mejeeji ati fun awọn musulumi


ستون سؤالا في أحكام الحيض والنفاس - يوربا


بيان الإسلام
Bayan AL-Islam

مؤسسة الشيخ محمد بن صالح العثيمين الخيرية
رحمه الله تعالى

# Ibeere ọgọta nipa awọn idajọ ẹjẹ nnkan oṣu ati ibimọ

شركاء التنفيذ:

دار الإسلام جمعية الربوة رواد الترجمة المحتوى الإسلامي

يتاح طباعة هذا الإصدار ونشره بأي وسيلة مع

الالتزام بالإشارة إلى المصدر وعدم التغيير في النص.

Telephone: +966114454900

ceo@rabwah.sa

P.O.BOX: 29465

RIYADH: 11557

www.islamhouse.com

بسم الله الرحمن الرحيم

Pẹ̀lú orúkọ Ọlọhun Ajọkẹ-aye Àṣàkẹ́-ọ̀run

# Ọrọ iṣaaju

Ọpẹ ni fun Ọlọhun, ikẹ ati ọla ko maa ba Ojiṣẹ Ọlọhun Muhammad ọmọ Abdullahi ati awọn ara ile rẹ ati awọn saabe rẹ ati ẹni ti o ba rin lori oju ọna rẹ titi di ọjọ ẹsan, lẹyin naa:

Irẹ ọmọ iya mi Mùsùlùmí lóbìnrin!

Ni iwoye si ọpọlọpọ ibeere ti o n wa ba awọn onimimọ nipa alamọri awọn idajọ ẹjẹ nnkan oṣu nibi awọn ijọsin, a ri i pe ki a ko awọn ibeere ti o maa n pààrà ni gbogbo igba jọ, ati eyi ti o maa n ṣẹlẹ ni ọpọ igba láìní fà á gùn, ìyẹn ni láti ṣe e ni ṣókí.

Irẹ ọmọ iya mi Mùsùlùmí lóbìnrin!

A ṣe ojúkòkòrò láti ko wọn jọ; ki o le baa jẹ nnkan ti yoo wa ni arọwọto ni gbogbo igba, ìyẹn rí bẹ́ẹ̀ fun ṣíṣe pataki imọ agbọye ẹsin nibi ofin Ọlọhun, ki o le baa maa jọsin fun Ọlọhun lori imọ ati amọdaju

Akiyesi: Lójú ẹni ti o ba n ṣi iwe naa wo fun igba akọkọ, o le dà bíi pe awọn ibeere kan jẹ nnkan ti n paara, ṣugbọn lẹyin ironu si, yoo pada ri i pe alekun imọ kan n bẹ nibẹ nibi ìdáhùn kan si omiran, a ri i pe ki a ma fi ojú fò wọ́n ru.

Ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba Anabi wa Muhammad ati awọn ara ile rẹ ati awọn sọhaba rẹ lapapọ

*

# Ninu awọn idajọ ẹjẹ nnkan oṣu nibi irun ati awẹ

Ibeere akọkọ: Ti obinrin ba mọra ní kété ti alufajari bá yọ, ǹjẹ́ o maa kóra ro ti yoo si gba awẹ ọjọ yii, ti o si maa ní awẹ ọjọ yii, àbí o maa san an padà?

Idahun akọkọ: Ti obinrin ba mọra lẹyin yíyọ alufajari, ọrọ meji ni o n bẹ fun awọn onimimọ nipa kiko ara rẹ ro ni ọjọ yẹn:

Ọrọ akọkọ: Dajudaju ikoraro yoo maa jẹ dandan fun un ni eyi ti o ṣẹku ninu ọjọ yen, ṣugbọn wọn ko nii ka a fun un, bi ko ṣe pe idapada maa jẹ dandan fun un, eleyii ni eyi ti o gbajumọ ninu oju ọna Imam Ahmad- ki Ọlọhun kẹ ẹ-

Ọ̀rọ̀ keji: Dajudaju ikoraro o nii jẹ dandan fun un ni eyi ti o ṣẹku ninu ọjọ yẹn; nitori pe o jẹ ọjọ kan ti awẹ rẹ ko nii ni alaafia nibẹ; nitori pe o jẹ ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu ni ìbẹ̀rẹ̀ ọjọ́ náà, ko si si ninu awọn alaawẹ. Ti ko ba ti wa ni alaafia, anfaani kankan ko ṣẹku fun ikoraro, ati pe akoko yii jẹ akoko kan ti ko ni ọwọ lọ́dọ̀ rẹ; nitori pe o jẹ ẹni ti a pa laṣẹ lati má gba awẹ ni akọkọ ọsan, bi ko ṣe pe gbigba awẹ rẹ jẹ eewọ fun un ni akọkọ ọsan Awẹ ti sharia: Oun ni ikoraro kuro nibi awọn nnkan ti wọn le ba awẹ jẹ ni ti

ijọsin fun Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- lati igba ti alufajari ba ti yọ titi ti oorun yoo fi wọ

Ọ̀rọ̀ yii- gẹgẹ bi o ṣe ri i- ni o tẹsuwọn ju ọrọ ijẹ dandan ikoraro lọ, ati pe lori ọrọ mejeeji ni idapada ọjọ yii yoo ti jẹ dandan fun un

Ibeere keji: Ti ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu ba mọra, ti o wẹ lẹyin irun alufajari, ti o ki run, ti o pari awẹ ọjọ rẹ, njẹ idapada rẹ jẹ dandan fun un?

Idahun keji: Ti ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu ba mọra ṣiwaju yiyọ alufajari koda ko ṣe pe pẹlu iṣẹju kan, ṣugbọn o ni amọdaju nipa imọra, ti o ba jẹ inu Ramadan, dandan ni fun un ki o gba awẹ, awẹ rẹ ni ọjọ yẹn yoo ni alaafia, ti idapada rẹ ko nii jẹ dandan fun un; nitori pe o gba awẹ nigba ti o wa ni mimọ, koda ki o ma wẹ afi lẹyin yiyọ alufajari, ko si ẹṣẹ nibẹ Gẹgẹ bi o ṣe jẹ pe ti ọkùnrin ba jẹ oni janaba lara latara ibalopọ tabi ala, ti o wa jẹ saari, ti ko wẹ afi lẹyin yiyọ alufajari, awẹ rẹ ni alaafia Pẹlu ibamu yii, mo fẹ lati pe yin si akiyesi si alamọri mìíràn kan lọdọ awọn obìnrin ti ẹjẹ nnkan oṣu ba yọ si i ti o si ti gba awẹ ọjọ yẹn, apakan ninu awọn obinrin maa n lérò pe ti ẹjẹ nnkan oṣu ba yọ si i lẹyin ti o ba ṣinu ṣiwaju ki o to ki irun Ishai pe awẹ rẹ ọjọ yẹn ti bajẹ Èyí ko si ẹri fun un, bi ko ṣe pe ẹjẹ

nnkan oṣu ti o ba yọ si i lẹyin wiwọ oòrùn, koda ko ṣe pe pẹlu iṣẹju aaya, dajudaju awẹ rẹ pe o si ni alaafia

Ibeere kẹta: Njẹ o jẹ dandan fun ẹni ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ lati gba awẹ ati ki irun ti o ba mọra ṣiwaju ogoji ọjọ?

Idahun kẹta: Bẹẹni, igba ti ẹni ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ ba mọra ṣiwaju ogoji ọjọ, o jẹ dandan fun un lati gba awẹ ti o ba jẹ inu Ramadan; o si jẹ dandan fun un lati kirun, o si lẹtọọ fun ọkọ rẹ lati ba a lopọ; nitori pe ẹni mimọ ni, ko si si nnkan ti yoo kọ awẹ lara rẹ, tabi nnkan ti yoo kọ ijẹ dandan irun fun un ati ṣíṣe ibalopọ ni ẹtọ

Ibeere kẹrin: Ti nǹkan oṣù obìnrin bá jẹ ọjọ mẹjọ tabi ọjọ meje, lẹyin naa o wa tẹsiwaju pẹlu rẹ ni ẹẹkan tabi ẹẹmeji tabi ju iyẹn lọ, ki ni idajọ naa?

Idahun kẹrin: Ti nǹkan oṣù obinrin yii ba jẹ ọjọ mẹfa tabi meje, lẹyin naa ti akoko yii wá gùn síi, ti o wa di ọjọ mẹjọ tabi mẹsan-an tabi mẹwaa tabi mọ́kànlá, ko nii kirun titi yoo fi mọ Ìyẹn rí bẹ́ẹ̀; nitori pe Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ko pa aala kan pato nibi ẹjẹ nnkan oṣu, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga sọ pe-:

﴿وَيَسْـَٔلُونَكَ عَنِ ٱلْمَحِيضِۖ قُلْ هُوَ أَذًى...﴾[البقرة: 222]

{Wọ́n sì ń bi ọ́ léèrè nípa ǹǹkan oṣù (obìnrin). Sọ pé: "Ìnira ni (sísúnmọ́ wọn lásìkò náà)}[Surah Al-Baqarah: 222] Gbogbo igba ti ẹjẹ yii ba n ṣẹku, obinrin naa maa wa lori iṣesi rẹ titi yoo fi mọ, ti yoo wẹ, lẹyin naa yoo kirun, ti o ba yọ si i ni oṣu keji ti o din si iyẹn, yoo wẹ ti o ba ti mọ, koda ki o ma jẹ lori akoko ti o ṣiwaju

Nnkan ti o ṣe koko ni pe dajudaju obinrin gbogbo igba ti ẹjẹ nnkan oṣu ba ti n bẹ pẹlu rẹ, ko nii kirun, boya ẹjẹ nnkan oṣu naa papọ mọ àṣà rẹ ti o ṣiwaju, tabi o lekun si i, tabi o din, ti o ba ti mọ yoo kirun

Ibeere karun-un: Obinrin ti ẹjẹ ibimọ n da lara rẹ, njẹ yoo jokoo fun ogoji ọjọ ti ko nii kirun tabi gba awẹ, tabi ohun ti a maa woye si ni dida ẹjẹ rẹ, gbogbo igba ti o ba ti da, yoo mọra, yoo si kirun? Ati pe ki ni akoko ti o kere julọ fun imọra?

Idahun karun-un: Ẹni ti ẹjẹ ibimọ n da lara rẹ ko si asiko kan ti o ni aala fun un, bi ko ṣe pe gbogbo igba ti ẹjẹ naa ba ti n bẹ yoo jokoo, ti ko nii kirun, ko nii gba awẹ, ọkọ rẹ ko si nii sunmọ ọn

Ti o ba ri mimọ- koda ko jẹ ṣiwaju ogoji ọjọ-, ko da ki o ma jokoo afi fun ọjọ mewaa tabi ọjọ márùn-ún- dajudaju yoo kirun, yoo gba awẹ, ọkọ rẹ yoo ba a lopọ, ko si ẹṣẹ nibi ìyẹn-

Nnkan ti o jẹ koko ni pe dajudaju ẹjẹ ibimọ jẹ alamọri kan ti a maa n mọ ọn lara, ti awọn idajọ n so pọ mọ bibẹ rẹ ati aisi rẹ, gbogbo igba ti o ba ti n bẹ, awọn idajọ rẹ yoo maa fi ẹsẹ rinlẹ, gbogbo igba ti o ba ti mọra kuro nibẹ yoo bọ kúrò nibi awọn ìdájọ́ rẹ.

Ṣugbọn ti o ba ju ọgọ́ta ọjọ lọ, yoo di ẹni ti ẹjẹ awaada n da lara rẹ, yoo jokoo ni odiwọn ohun tí ó bá ṣe déédéé nǹkan oṣù rẹ sọ́, lẹyin naa yoo wẹ, yoo si kirun

Ibeere kẹfa: Ti ẹjẹ kékeré díẹ̀ ba jade lati ara obinrin ni ọsan Ramadan, ti ẹjẹ yii wa tẹsiwaju pẹlu rẹ fun gbogbo oṣu Ramadan ti o si n gba awẹ, njẹ awẹ rẹ ni alaafia?

Idahun kẹfà: Bẹẹni, awẹ rẹ ni alaafia, ṣugbọn awọn ẹ̀kán ẹ̀jẹ̀ yii ko jẹ nnkankan; nitori pe o n jade lati inu awọn iṣan, wọn gba ọrọ wa lati ọdọ Aliy ọmọ Abu Talib- ki Ọlọhun yọnu si i- pe o sọ pe: Dajudaju awọn ẹ̀kán ẹ̀jẹ̀ ti o da gẹgẹ bii àmúrun yii, kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu. Báyìí ni wọn ṣe sọ nipa rẹ (ki Ọlọhun yọnu si i).

Ibeere keje: Ti ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu tabi ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ ba mọ ṣiwaju alufajari, ti ko ba wẹ afi lẹyin alufajari, njẹ awẹ rẹ ni alaafia tabi ko ni?

Idahun keje: Bẹẹni, awẹ obinrin ti o n ṣe nnkan oṣu ni alaafia ti o ba mọ ṣiwaju alufajari, ti ko wẹ afi lẹyin yiyọ

alufajari, gęgę bęę naa ni ęni ti ęję ìbímọ n da lara rę; nitori pe nígbà naa o wa ninu awọn alaawę, o jọ ęni ti janaba wa ni ara rę, ti alufajari ba yọ ti o si ję oni janaba lara, dajudaju awę rę ni alaafia; Fun ọrọ Ọlọhun ti O sọ pe:

﴿... وَلَا تُبَٰشِرُوهُنَّ وَأَنتُمۡ عَٰكِفُونَ فِي ٱلۡمَسَٰجِدِۗ تِلۡكَ حُدُودُ ٱللَّهِ فَلَا تَقۡرَبُوهَاۗ كَذَٰلِكَ يُبَيِّنُ ٱللَّهُ ءَايَٰتِهِۦ لِلنَّاسِ لَعَلَّهُمۡ يَتَّقُونَ١٨٧﴾ [البقرة: 187]

{Ní báyìí, ę súnmọ́ wọn, kí ę sì wá ohun tí Allāhu kọ mọ yín (ní ọmọ). Ę ję, ę mu títí ę ó fi rí ìyàtọ̀ láàárin òwú funfun (ìyęn, ìmọ́lę̀ òwúrọ̀) àti òwú dúdú (ìyęn, òkùnkùn òru) ní àfę̀mọ́júmọ́}[Surah Al-Baqarah: 187] Nigba ti Ọlọhun- ti ọla Rę ga- șe iyọnda ibalopọ titi ti alufajari o fi han, o ję dandan nibi ìyęn ki iwę ma waye afi lęyin yiyọ alufajari, fun hadisi 'Aaisha- ki Ọlọhun yọnu si i- pé Anabi- ki ikę Ọlọhun ati ọla Rę maa ba a- maa n ji ni oni janaba lara latara ibalopọ awọn ara ile rę ti o si n gba awę Ìtumọ̀ rę ni pé: Anabi- ki ikę Ọlọhun ati ọla Rę maa ba a- ko nii wę latara janaba afi lęyin yiyọ owurọ.

Ibeere kęjọ: Ti obinrin ba funra mọ ęję, ti ko jade șiwaju wiwọ oòrùn, tabi ki o ni ìmọ̀lára ìnira nǹkan oșù, nję awę rę ọjọ yęn ni alaafia, àbí idapada rę maa ję dandan fun un?

Idahun kęjọ: Ti obinrin ti o mọ ba ni ìmọ̀lára pe ęję nnkan oșu fę wá ti o si ję alaawę, șugbọn ko jade afi lęyin

wiwọ oòrùn, àbí ó ni ìmọ̀lára ìnira nǹkan oṣù, ṣùgbọ́n ko jade afi lẹyin wiwọ oòrùn, dajudaju awẹ rẹ ọjọ yẹn ni alaafia, ti idapada rẹ ko si jẹ dandan fun un ti o ba jẹ ọranyan, ti ẹsan rẹ ko si bajẹ pẹlu rẹ ti o ba jẹ aṣegbọrẹ.

Ibeere kẹsàn-án Ti obinrin ba ri ẹjẹ, ti ko da a loju pe ẹjẹ nnkan oṣu ni, ki ni idajọ awẹ rẹ ni ọjọ yẹn?

Idahun kẹsàn-án Awẹ rẹ ni ọjọ yẹn ni alaafia; nitori pe ipilẹ ni aisi ẹjẹ nnkan oṣu titi yoo fi han si i pe ẹjẹ nnkan oṣu ni

Ibeere kẹwàá Nigba miiran obinrin maa n ri oripa kekere kan fun ẹjẹ tàbí ẹ̀kán ti o kéré gan ni àsìkò ọtọọtọ nínú ọjọ́ kan, nigba mii o le ri i ni asiko nnkan oṣu ti ko i tîi ṣan jade, nigba mii o le ri i ni asiko ti kii ṣe ti nǹkan oṣù, ki ni idajọ awẹ rẹ ni awọn iṣesi mejeeji naa?

Idahun kẹwàá Idahun lori iru ibeere yii ti ṣaaju laipẹ yìí, ṣugbọn o ṣẹku pe ti o bajẹ pe awọn ẹ̀kán ẹ̀jẹ̀ yii wa ni awọn ọjọ nǹkan oṣù, yoo ka a si ara ẹjẹ nnkan oṣu ti o mọ ọn; torí pé ó máa jẹ ẹjẹ nnkan oṣu ni.

Ibeere kọkànlá Ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu ati ẹni ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ, ǹjẹ́ wọn maa jẹun tabi mu ni ọsan Ramadan bi?

Idahun kọkànlá Bẹẹni, wọn maa jẹun wọn si maa mu ni ọsan Ramadan, ṣugbọn eyi ti o daa julọ ni ki o jẹ ni kọkọ ti ẹnikẹni ninu awọn ọmọde ba wa ni ọdọ rẹ ninu ile; nitori pe iyẹn maa da iruju sílẹ̀ fun wọn.

Ibeere kejila: Ti ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu tabi ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ ba mọ ni asiko Asr, njẹ irun Zuhr pẹlu Asr jẹ dandan fun un, tabi nnkankan ko jẹ dandan fun un yatọ si irun Asr nikan?

Idahun kejila Eyi ti o tẹsuwọn julọ nibi ọ̀rọ̀ yii ni pe: Nǹkan kan ko jẹ dandan fun un yatọ si irun Asr nikan; nitori pe ko si ẹri kankan lori jijẹ dandan irun Zuhr, ati pe ipilẹ ni ki ọrùn ó mọ́, lẹyin naa Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe: "Ẹnikẹni ti o ba ba rakaa kan ninu Asr ṣiwaju ki oòrùn to wọ, o ti ba Asr". Ko sọ pe o ba Zuhr, ti o ba ṣe pe Zuhr jẹ dandan ni, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ko ba ṣe alaye rẹ, ati pe nitori pe obinrin ti o ba ṣe nnkan oṣu lẹyin wiwọle asiko Zuhr, nnkankan ko jẹ dandan fun un afi sisan irun Zuhr yatọ si irun Asr, bi o ti lẹ jẹ pe wọn maa n da Zuhr pọ mọ Asr, ko si si iyatọ laaarin rẹ ati laaarin aworan ti ibeere waye lori rẹ

Lori eyi, ọrọ ti o tẹsuwọn julọ maa jẹ pe irun Asr nikan ni o maa jẹ dandan fun un; fun itọka ọrọ Ọlọhun ati ìfiwéra, gẹgẹ bẹẹ ni ọrọ naa ṣe ri ti o ba mọra ṣiwaju wiwọle asiko

'Ishai, ko si nnkankan ti o jẹ dandan fun un afi 'Ishai, ti irun Magrib ko si jẹ dandan fun un

Idahun kẹtàlá: Apakan ninu awọn obinrin ti wọn n ba oyun jẹ, iṣesi naa ko le ju: Ninu ki obinrin ba oyun jẹ ṣiwaju ki ọlẹ̀ o to pé ní ẹ̀dá, tabi ki o jẹ pe lẹyin ti o ti pe ni ẹ̀dá, ti ìṣètò si ti hàn nibẹ, ki ni idajọ awẹ rẹ ni ọjọ yẹn ti o ba oyun jẹ nibẹ, ati awẹ ọjọ ti o ri ẹjẹ nibẹ?

Idahun kẹtàlá: Ti ọlẹ̀ naa ko ba i tii pé ni ẹ̀dá, dajudaju ẹjẹ rẹ ko kii ṣe ẹjẹ ibimọ, lori eyi yoo gba awẹ yoo si kirun, awẹ rẹ si ni alaafia

Ti ọlẹ̀ naa ba ti pé ni ẹ̀dá, dajudaju ẹjẹ naa maa jẹ ẹjẹ ibimọ, ko lẹtọọ fun un lati kirun nibẹ tabi lati gba awẹ

Ofin ti o de ọrọ yii ni pe: Ti ẹ̀dá ọlẹ naa ba ti pe, ẹjẹ naa maa jẹ ẹjẹ ibimọ, ti ko ba tii pé ni ẹ̀dá, dajudaju ẹjẹ rẹ ko kii ṣe ẹjẹ ibimọ, ti ẹjẹ naa ba jẹ ẹjẹ ibimọ, wọn ṣe ni eewọ fun un nnkan ti wọn ṣe ni eewọ fun ẹni ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ, ti ko ba kii ṣe ẹjẹ ìbímọ, ìyẹn ko nii jẹ eewọ fun un.

Ibeere kẹrinla: Dida ẹjẹ latara oloyun ni ọsan Ramadan, njẹ yoo lapa lara awẹ rẹ?

Ìdáhùn kẹrinla: Ti ẹjẹ nnkan oṣu ba jade ti obinrin si jẹ alaawẹ, dajudaju awẹ rẹ maa bajẹ; fun ọrọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe: “Ṣe ko kii ṣe pe ti o ba ti

ṣe nnkan oṣu ko nii kirun, ko si nii gba awẹ ni?" Fun idi eyi wọn ka a si ara awọn nnkan ti n ba awẹ jẹ, ati pe ẹjẹ ìbímọ da gẹgẹ bii rẹ, ati pe jidade ẹjẹ nnkan oṣu ati ìbímọ n ba awẹ jẹ

Jijade ẹjẹ latara oloyun ni ọsan awẹ ti o ba jẹ nnkan oṣu da gẹgẹ bii ẹjẹ nnkan oṣu ẹni ti kii ṣe oloyun, o n túmọ̀ si pe: Yoo lapa lara awẹ rẹ, ti ko ba kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu ko nii lapa lara rẹ

Ati pe ẹjẹ nnkan oṣu ti o rọrun ki o waye lati ọdọ oloyun ni ki o jẹ ẹjẹ nnkan oṣu ti o n tẹle ara wọn ti ko da lara rẹ lati igba ti o ti loyun, bi ko ṣe pe o n da lara rẹ ni awọn asiko nǹkan oṣù rẹ, eyi jẹ ẹjẹ nnkan oṣu lori ọrọ ti o tẹsuwọn julọ, awọn idajọ ẹjẹ nǹkan oṣu maa fi ẹsẹ rinlẹ fun un

Ṣugbọn ti o ba ti da lara rẹ, lẹyin naa ti o wa n ri ẹjẹ lẹyin iyẹn, kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu nìyẹn, dajudaju eyi ko nii lapa lara awẹ rẹ; torí pé ko kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu

Ibeere karundinlogun: Ti obinrin ba ri ẹjẹ kan ni asiko nnkan oṣu rẹ ni ọjọ kan, ti ko wa ri ẹjẹ ni ọjọ ti o tẹle e ni gbogbo ọsan, ki ni o jẹ dandan fun un lati ṣe?

Idahun karundinlogun: Eyi ti o han ni pe mimọ yii tabi gbígbẹ ti o ṣẹlẹ si i ni awọn ọjọ nnkan oṣu rẹ maa tẹle

nnkan oṣu ni, a ko nii ka a si mimọ, lori eyi yoo wa ni ẹni tí yoo jáwọ́ kúrò nibi gbogbo nǹkan ti ẹni tí ń ṣe nǹkan oṣù kò gbọ́dọ̀ ṣe. Awọn apakan ninu awọn onimimọ sọ pe: Ẹni ti o ba ri ẹjẹ ni ọjọ kan, ti o ri mimọ ni ọjọ miiran, ẹjẹ náà maa jẹ ẹjẹ nnkan oṣu, mimọ naa si maa jẹ imọra titi yoo fi pe ọjọ marundinlogun, Ti o ba ti pe ọjọ marudinlogun, nnkan ti o ba wa lẹyin rẹ ti di ẹjẹ awaada, eleyii ni nnkan ti o gbajugbaja ninu oju ọna Imam Ahmad ọmọ Hanbal- ki Ọlọhun kẹ ẹ-

Ibeere kẹrindinlogun: Ni awọn ọjọ ikẹyin nibi ẹjẹ nnkan oṣu ati ṣiwaju mimọ ti obinrin ko nii ri oripa ẹjẹ, njẹ yoo gba awẹ ọjọ yẹn ti ko si tii ri omi funfun, àbí ki ni yoo ṣe?

Idahun kẹrindinlogun: Ti o ba jẹ ninu iṣesi rẹ ni ki o ma ri omi funfun- gẹgẹ bi o ṣe wa fun awọn obìnrin kan- yoo gba awẹ, ti o ba wa jẹ pe nínú iṣesi rẹ ni ki o ri omi funfun, ko nii gba awẹ títí ti yoo fi ri omi funfun

Ibeere kẹtadinlogun: Ki ni idajọ kika Kuraani ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu ati ẹni ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ ni ti wiwo ati hiha ni iṣesi kò-ṣeé-má-ṣe, bii ki o jẹ ọmọ akẹkọọ lobinrin tabi olukọ lobinrin?

Idahun kẹtadinlogun: Ko si ẹṣẹ fun obinrin ti o n ṣe nnkan oṣu tabi ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ nibi kika Kuraani ti

o ba bukaata si i, gẹgẹ bii olukọ lobinrin, tabi ki o jẹ akẹ́kọ̀ọ́ ti o n ka ìpín rẹ ti kò le má kà ni alẹ ati ọsan,

Şugbọn kika Kuraani lati wa ẹsan- eyi ti o daa julọ ni ki o ma ṣe e; nitori pe ọpọlọpọ ninu awọn onimimọ tabi eyi ti o pọ̀ jù nínú wọn ri pe ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu, kika Kuraani ko lẹtọọ fun un

Ibeere kejidinlogun: Njẹ pipaarọ awọn aṣọ rẹ jẹ dandan fun ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu lẹyin mimọ, pẹlu nini imọ pe dajudaju ẹjẹ ko da si i tabi ẹgbin?

Idahun kejidinlogun: Iyẹn ko jẹ dandan fun un; nitori pe nnkan oṣu ko lee ko ẹgbin ba ara, bi ko ṣe pe ẹjẹ nnkan oṣu maa n ko ẹgbin ba nnkan ti o ba kàn nikan ni, fun idi eyi, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- paṣẹ fun awọn obinrin ti ẹjẹ nnkan oṣu ba da si aṣọ wọn lati fọ wọn, ki wọn si ki irun ninu awọn aṣọ wọn

Ibeere kọkandinlogun: Obinrin kan ja awẹ ninu Ramadan fun ọjọ meje ti o si jẹ ẹni ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ, ko si san an pada titi ti Ramadan keji fi wọle ba a, o tun ja awẹ ọjọ méje mìíràn ninu Ramadan keji ti o jẹ ẹni ti o n fun ọmọ ni ọyan, ti ko san an pada pẹlu awijare aisan kan ti o mu u, ki ni nnkan ti o jẹ dandan fun un ki Ramadan kẹta si ti fẹ wọle? Ẹ ṣe wa ni anfaani, Ọlọhun A san yin ni ẹsan.

Idahun kọkandinlogun: Ti obinrin yii ba ri bi o ṣe sọ nipa ara rẹ̀- pe oun wa ninu aisan, ti ko si ni agbara ati san an pada- dajudaju yoo gba a pada ni igba ti o ba ti ni ikapa; nitori pe o jẹ ẹni ti a fun ni awijare, koda ki Ramadan keji wọle Ṣugbọn ti o ba ṣe pe ko si awijare fun un, bi ko ṣe pe o kan n wa àwíjàre lasan ni ti ko si ni àkàkún, ko lẹtọọ fun un lati lọ sisan awẹ pada lara di Ramadan keji " 'Aaisha- ki Ọlọhun yọnu si i- sọ pe: Mo maa n jẹ awẹ, ti mi ko nii ni ikapa lati da a pada afi ninu Sha'ban

"Lori eyi, o jẹ dandan fun obinrin naa lati kiyesi ara rẹ, ti ko ba si awijare fun un o ti jẹ ẹlẹṣẹ, o jẹ dandan fun un lati ronupiwada lọ si ọdọ Ọlọhun, ki o tete lọ san nnkan ti o n bẹ lọrun rẹ pada ninu awẹ, ṣùgbọ́n ti o ba ni awijare ko si ẹṣẹ fun un, ko da ki o lọ ọ lara fun ọdun kan tabi ọdun meji

Ibeere ogun: Apakan awọn obinrin, Ramadan keji maa wọle ba wọn ti wọn ko si tii gba awọn ọjọ kan ninu Ramadan ti o ṣáájú, ki ni nnkan ti o jẹ dandan fun wọn?

Idahun ogun: " Nnkan ti o jẹ dandan fun wọn ni: Ironupiwada lọ si ọdọ Ọlọhun kuro nibi iṣẹ yii; nitori pe ko lẹtọọ fun ẹni ti o jẹ Ramadan lati lọ ọ lara di Ramadan keji laisi àwíjàre kankan; fun ọrọ 'Aaisha- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe: Mo maa n jẹ awẹ Ramadan, ti mi o si nii ni ikapa lati da a pada afi ninu Sha'ban.

Eyi n tọka si pe lilọ ọ lara ko rọrun di ẹyin Ramadan keji, dandan ni fun un láti ronupiwada si ọdọ Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- nibi nǹkan ti o ṣe, ki o si san awọn ti o gbe ju silẹ pada lẹyin Ramadan keji

Ibeere kọkanlelogun: Ti obinrin ba bẹ̀rẹ̀ nnkan oṣu ni aago kan ọsan fun apẹrẹ, ti ko si tii ki irun Zuhr, njẹ sisan irun yẹn pada jẹ dandan fun un lẹyin imọra bi?

Idahun kọkanlelogun: Iyapa ẹnu wa nibi eyi laaarin awọn onimimọ, o n bẹ ninu wọn ẹni ti o sọ pe: Ko jẹ dandan fun un lati san irun yii pada; nitori pe ko ṣe àseètó, ko si da ẹṣẹ; torí pé o lẹtọọ fun un lati lọ irun lara di ipari asiko rẹ O n bẹ ninu wọn ẹni ti o sọ pe: Sisan an pada jẹ dandan fun un, o n túmọ̀ si: Sisan irun yẹn pada; fun akotan ọrọ rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-: "Ẹni ti o ba ba ra'kah kan ninu irun ti ba irun"

Ohun ti o fi ni lọ́kàn balẹ̀ ni: Ki o san an pada; nitori pe o jẹ irun ẹyọkan, ti ko si wahala nibi sisan an pada

Ibeere kejilelogun: Ti oloyun ba ri ẹjẹ ṣiwaju ibimọ pẹlu ọjọ kan tabi meji, njẹ yoo gbe irun ati awẹ ju silẹ nitori rẹ, àbí ki ni?

Idahun kejilelogun: Ti oloyun ba ri ẹjẹ ṣiwaju ibimọ pẹlu ọjọ kan tabi meji, ti irora ibimọ si wa pẹlu rẹ, dajudaju ẹjẹ

ìbímọ ni, yoo gbe irun ati awẹ ju silẹ nitori rẹ, ti ko ba si irora ibimọ pẹlu rẹ, dajudaju ẹjẹ ibajẹ ni, a o nii ka a kun, ko si nii kodi rẹ kuro nibi awẹ tabi irun

Ibeere kẹtalelogun: Ki ni o ri si lilo awọn ogun oni koro láti dènà nǹkan oṣù; nitori gbigba awẹ pẹlu awọn eniyan?

Idahun kẹtalelogun: Emi n ṣe ikilọ kuro nibi eyi; nítorí pe inira ti o tobi ni o n bẹ nibi awọn ogun oni koro yìí, o fi ẹṣẹ rinlẹ lọdọ mi lati ọdọ awọn dokita. A maa sọ fun obinrin pe: Eyi jẹ nnkan ti Ọlọhun ti kọ lori awọn ọmọbinrin Anọbi Adam, gba tito pẹlu nnkan ti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- kọ, gba awẹ nigba ti ko ba si idiwọ, ti idiwọ ba ti waa wa, ki o yaa já awẹ ni ẹni tí yoo yọnu si nnkan ti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-kadara

Ibeere kẹrinlelogun: Obìnrin kan, lẹyin oṣu meji ninu ẹjẹ ibimọ, ati lẹyin ti o ti mọ́, o bẹrẹ si nii maa ri awọn ẹ̀kán kekere ninu ẹjẹ, njẹ yoo ja awẹ, ti ko si nii kirun bi? Abi ki ni yoo ṣe?

Idahun kẹrinlelogun: Awọn isoro awọn obinrin nibi ẹjẹ nnkan oṣu ati ìbímọ jẹ ibudo kan ti ko si ẹni ti o le wẹ ẹ ja, ninu awọn okunfa rẹ ni: Lilo awọn ogun oni koro ti wọn maa n kọdi oyun ati ẹjẹ nnkan oṣu, awọn eniyan ko mọ iru awọn isoro ti wọn pọ yii, Òótọ́ ni pe awọn isoro yii ko yẹ ko gbo ni nnkan ti o ti n bẹ lati igba igbedide Ojiṣẹ Ọlọhun-

ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- kódà o ti n bẹ lati ìgbà tí obìnrin ti n bẹ, ṣùgbọ́n pipọ rẹ bi o ṣe tó yii, ti ọmọniyan ko ri ojútùú rẹ, o jẹ nnkan ti n ba ni nínú jẹ. Ṣugbọn òfin gbogbogboo ni pe: Ti obinrin ba ti mọ, ti o ti ri mimọ ti o daju nibi ẹjẹ nnkan oṣu ati nibi ẹjẹ ìbímọ- nnkan ti mo gba lero pẹlu mimọ nibi ẹjẹ nnkan oṣu ni: Jíjáde omi funfun, oun ni omi funfun kan ti awọn obinrin mọ ọn- gbogbo nǹkan tí o ba wa lẹyin mimọ bii omi ti o fẹ́ dudu, tabi pupa, tabi ẹ̀kán, tabi omi tútù, gbogbo eyi kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu, ko si nii kọdi irun ati awẹ ati ìbálòpọ̀; tori pe kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu, Ummu 'Atiyyah sọ pe: A wa ko ki n ka omi pupa ati omi ti o fẹ dudu si nnkankan. Bukhari ni o gbe e jade, Abu Daud ṣe alekun: Lẹyin mimọ. Sanadu rẹ ni alaafia Lori eyi a maa sọ pe: Gbogbo nnkan ti o ṣẹlẹ lẹyin mimọ ti o daju ninu awọn nnkan yii ko lee ko inira ba obinrin, ko lee kọdi rẹ nibi irun rẹ ati awẹ rẹ ati sisunmọ ọkọ rẹ mọ ọn, ṣugbọn o jẹ dandan lati ma kanju titi yoo fi ri mimọ; Nitori pe apakan ninu awọn obinrin, ti ẹjẹ ba ti gbẹ lara rẹ yoo tete lọ wẹ ṣiwaju ki o to ri mimọ Fun idi eyi awọn obinrin awọn sọhaba maa n fi Kursuf ranṣẹ si iya awọn olugbagbọ Aaisha- ki Ọlọhun yọnu si i-, o n túmọ̀ si: Owu ti ẹjẹ n bẹ nibẹ, o maa wa sọ fun wọn pe: Ẹ ma kanju titi ti ẹ fi maa ri omi funfun.

Ibeere karundinlọgbọn: Àwọn kan ninu awọn obìnrin maa n ri ẹjẹ lọ, nígbà mii o maa da fun ọjọ kan tabi ọjọ meji, lẹyin naa yoo pada, ki ni idajọ nibi iṣesi yii nibamu si awẹ ati irun ati awọn ijọsin yoku?

Idahun karundinlọgbọn: Nnkan ti a mọ lọdọ ọpọlọpọ ninu awọn onimimọ ni pe: Ti obinrin ba ni iṣesi, ti iṣesi rẹ wa pari, yoo wẹ, yoo si kirun, yoo si gba awẹ, nnkan ti o ba ri lẹyin ọjọ meji tabi ọjọ mẹta ko kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu; nitori pe ọjọ ti o kere julọ lọdọ awọn onimimọ ni ọjọ mẹ́tàlá

Apakan ninu awọn onimimọ sọ pe: Dajudaju gbogbo igba ti o ba ri ẹjẹ oun ni ẹjẹ nnkan oṣu, gbogbo igba ti o ba ti mọra kuro nibẹ o ti jẹ ẹni ti o mọ, ti ọjọ mẹ́tàlá ko ba i tii si laaarin nnkan oṣu méjèèjì.

Ibeere kẹrindinlọgbọn: Ewo ni o daa julọ fun obinrin: Lati ki irun ni alẹ Ramadan ni ile rẹ, tabi ni mọsalasi, pataki julọ ti awọn waasi ati awọn iranti ba wa nibẹ? Ki ni ìmọ̀ràn rẹ fun awọn obinrin ti wọn n kirun ni awọn mọsalasi?

Idahun kẹrindinlọgbọn: Eyi ti o daa julọ ni ki o kirun ni ile rẹ; fun kikari ọrọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti o sọ pe: "Awọn ile wọn daa julọ fun wọn" Ati pe ìjáde obinrin ko la ninu fitina ni ọpọlọpọ igba, ki obinrin ni ile rẹ ni oore fun un ju ki o jade fun irun lọ si mọsalasi, ati

pe o rọrùn lati ri àwọn waasi ati hadiisi naa ni ipasẹ kasẹẹti.

Ìmọ̀ràn mi fun awọn ti wọn n kirun ni mọsalasi ni: Ki wọn jade lati inu ile wọn ti wọn ko nii fi ẹṣọ wọn han, tabi lo lọfinda

Ibeere kẹtadinlọgbọn: Ki ni idajọ titọ oúnjẹ wo ni ọsan Ramadan, ti obìnrin naa si jẹ alaawẹ?

Idahun kẹtadinlọgbọn: Idajọ rẹ ni pe: Ko si ohun ti o burú nibẹ; fun ini bukaata si i, ṣugbọn yoo tu nnkan ti o tọ́wò danu

Ibeere kejidinlọgbọn: Obìnrin kan ti ijanba ṣẹlẹ si i, ti o si wa ni ibẹrẹ oyún, ọmọ naa si jabọ lẹyin jíjáde ẹjẹ ti o pọ ga, njẹ o jẹ dandan fun un lati ja awẹ, tabi ki o tẹsiwaju pẹlu awẹ? Ti o ba ja awẹ, njẹ ẹṣẹ n bẹ fun un bi?

Idahun kejidinlọgbọn: A maa sọ pe: Dajudaju oloyun ko le ṣe nnkan oṣu, gẹgẹ bi Imam Ahmad ṣe sọ: Awọn obinrin maa n da oyún mọ pẹlu ki nnkan oṣu dúró. Ati pe nnkan oṣu- gẹgẹ bi awọn onimimọ ṣe sọ- Ọlọhun- ìbùkún ni fun Un ti ọla Rẹ ga- ṣẹda rẹ fun ọgbọn jijẹ oúnjẹ ọmọ ninu ikun iya rẹ, ti oyun ba ti bẹrẹ, ẹjẹ nnkan oṣu maa da

Ṣugbọn awọn obinrin kan maa n ṣe nnkan oṣu lọ lori iṣesi rẹ gẹgẹ bi o ṣe wa ṣiwaju oyun, idajọ eléyìí ni pe

nǹkan oṣù rẹ ni alaafia; torí pé ẹjẹ nnkan oṣu rẹ n lọ, oyun naa ko lapa lara rẹ, nnkan oṣu yii maa kọ gbogbo nnkan ti nǹkan oṣù ẹni tí ko loyun maa n kọ, o si maa sọ ohun ti o ba maa n sọ di dandan di dandan, o si maa mu kuro ohun ti o ba maa n mu kúrò.

Ni akotan: Dajudaju ẹjẹ ti o n jade latara oloyun jẹ iran meji:

Iran kan jẹ ẹjẹ nnkan oṣu, oun ni eyi ti o tẹsiwaju pẹlu rẹ gẹgẹ bi o ṣe wa ṣiwaju oyun, itumọ iyẹn ni pe: Oyun ko lapa lara rẹ, yoo si jẹ ẹjẹ nnkan oṣu.

Iran keji: Ẹjẹ kan ti o ṣẹlẹ si oyun lojiji, ninu ki o jẹ pe pẹlu okunfa ijanba kan, tabi gbigbe nnkankan, tabi jijabọ lati ori nnkankan ati nnkan ti o jọ ọ, ẹjẹ rẹ ni eyi kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu, bi ko ṣe pe ẹjẹ iṣan ni Lori eyi ko lee kọdi rẹ nibi irun, tabi awẹ, bi ko ṣe pe o wa ninu idajọ awọn ti wọn mọ

Ṣugbọn ti ọmọ ba jabọ latara ijanba naa tabi oyun ti o wa ni ikun rẹ, yoo wa lori nnkan ti awọn onimimọ sọ pe: Ti o ba jade ti ẹda ọmọniyan ti han nibẹ, wọn maa ka ẹjẹ rẹ lẹyin jíjáde rẹ si ẹjẹ ìbímọ, yoo gbe irun ati awẹ ju silẹ ti ọkọ rẹ si maa jina si i titi ti o fi maa mọ.

Ti ọlẹ̀ naa ba jade ti ko si tii pé ni ẹ̀dá, wọn ko nii ka si ẹjẹ ìbímọ, bi ko ṣe pe oun ni ẹjẹ ibajẹ, ko nii kọdi rẹ kuro

nibi irun, tabi kuro nibi awẹ, tabi kuro nibi nnkan ti o yatọ si mejeeji

Awọn onimimọ sọ pe: Asiko ti o kere julọ ti pípé ni ẹ̀dá maa n han nibẹ ni: Ọjọ mọkanlelọgọrin; torí pe ọlẹ̀ wa ninu ikun iya rẹ Gẹgẹ bi Abdulahi ọmọ Mas'ud- ki Ọlọhun yọnu si i- ṣe sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ba wa sọrọ, oun si ni olododo ti a sọ òdodo fun, o sọ pe: “Dajudaju ẹni kọ̀ọ̀kan ninu yin, wọn máa ko iṣẹda rẹ jọ sinu iya rẹ fun ogoji ọjọ ni omi lọgbọ lọgbọ, lẹyin naa yoo di ẹjẹ kiki bii iyẹn, lẹyin naa yoo di báàṣí ẹran bii ìyẹn, lẹ́yìn náà wọn maa gbe mọlaika kan dide si i, wọn maa pa a laṣẹ pẹlu awọn gbolohun mẹrin kan, wọn maa kọ arisiki rẹ, ati igba ti yoo lo laye, ati iṣẹ rẹ ati boya oloriburuku ni tabi oloriire ni”. Ko rọrun lati ṣẹda rẹ ṣiwaju iyẹn, eyi ti o pọ ju ni pe pípé ni ẹ̀dá ko nii han ṣiwaju ààdọ́rùn-ún ọjọ, gẹgẹ bi apakan awọn onimimọ ṣe sọ

Ibeere kọkandinlọgbọn: Obinrin kan ni mi, mo bi ọmọ ni ọsu kẹta lati ọdun kan sẹ́yìn, mi ko kirun titi ti mo fi mọ, wọn si ti sọ fun mi pe: O jẹ dandan fun ẹ lati kirun. Ki ni maa ṣe, emi ko mọ onka awọn ọjọ naa geerege?

Idahun kọkandinlọgbọn: Nnkan ti a mọ lọdọ awọn onimimọ ni pe: Dajudaju obinrin ti oyun rẹ ba walẹ ni ọsu

kẹta, ko nii kirun; nitori pe obinrin ti ọlẹ̀ inu rẹ ba bọ́ sílẹ̀ ti ẹ̀dá rẹ si ti pe, dajudaju ẹjẹ ti o ba n jade latara rẹ yoo maa jẹ ẹjẹ ibimọ, ko si nii kirun.

Awọn onimimọ sọ pe: O rọrun ki ṣiṣẹda ọlẹ̀ han ti o ba ti pe ọjọ mọkanlelọgọrin, eyi si kere si oṣu mẹta, ti o ba mọ amọdaju pe ọlẹ̀ naa jabọ ni oṣu kẹta, dajudaju nnkan ti o ṣẹlẹ si i maa jẹ ẹjẹ ibajẹ, ko nii gbe irun ju silẹ tori rẹ

Olubeere yii, o jẹ dandan fun un lati ranti nínú ẹ̀mí ara rẹ, ti ọlẹ̀ naa ba jabọ ṣiwaju ọgọrin ọjọ́, o maa san irun pada, ti ko ba mọ ọjọ meloo ni o gbe ju silẹ O maa ṣe odiwọn rẹ, yoo si ṣe ìwádìí, yoo si san ohun ti o ba bori nínú èrò rẹ pe oun ko ki i. Ibeere ọgbọn: Olubeere kan n sọ pe: Dajudaju lati igba ti awẹ ti jẹ dandan fun un ti o n gba awẹ Ramadan, ṣugbọn kii san awẹ awọn ọjọ ti o ja awẹ nibẹ tori nǹkan oṣù, torí aimọ onka awọn ọjọ ti o ja awẹ nibẹ ni o fi n beere itọsọna rẹ lọ si nnkan ti ṣíṣe rẹ jẹ dandan fun un nsinyii. Idahun ọgbọn: O ṣe wa laanu ki eyi maa ṣẹlẹ laaarin awọn obinrin olugbagbọ, dajudaju gigbe ju silẹ yii- ohun ti mo gba lero ni: Gbigbe sisan nnkan ti o jẹ dandan fun un ninu awẹ ju silẹ- ninu ki o jẹ ni ti aimọkan, tabi ki o jẹ ni ti àìní àkàkún, àdánwò ni mejeeji jẹ; nitori pe aimọkan, iwosan rẹ ni imọ ati ibeere Ṣugbọn àìní àkàkún, iwosan rẹ ni ibẹru Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- ati

ṣíṣe amujuto rẹ, ati ipaya iya Rẹ, ati titete lọ si ibi nnkan ti iyọnu rẹ n bẹ nibẹ

O jẹ dandan fun obinrin yii lati ronupiwada lọ si ọdọ Ọlọhun latara nnkan ti o ṣe, ki o si wa aforijin, ki o si ṣe ìwádìí àwọn ọjọ ti o gbe wọn ju silẹ bi o ba ṣe lágbára mọ, yoo si san wọn pada, pẹlu eyi ni ọrùn rẹ yóò fi mọ́, ki Ọlọhun gba ìrònúpìwàdà rẹ.

Ibeere kọkanlelọgbọn: Ki ni idajọ ti obinrin ba ri nnkan oṣu lẹyin wiwọle asiko irun? Njẹ o jẹ dandan fun un lati san an pada ti o ba ti mọ? Gẹgẹ bẹẹ naa ni ti o ba mọ ṣiwaju ki asiko irun tó lọ?

Idahun kọkanlelọgbọn: Akọkọ: Ti obìnrin ba ri nǹkan oṣù lẹyin wiwọle asiko irun, o jẹ dandan fun un ti o ba mọ lati san irun ti o ri nǹkan oṣù rẹ ni àsìkò rẹ pada, ti ko ba i tíì ki i ṣiwaju ki o to ri nǹkan oṣù Iyẹn ri bẹ́ẹ̀ fun ọ̀rọ̀ Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe: "Ẹni ti o ba ba rakah kan ninu irun ti ba irun" Ti obinrin ba ba ninu akoko irun odiwọn rakah kan, ti o wa ri nnkan oṣu ṣiwaju ki o to kirun, ti o ba ti mọ́ra, sisan an pada maa jẹ dandan fun un Ikeji: Ti o ba mọra kuro nibi nnkan oṣu ṣiwaju jijade akoko irun, sisan irun yẹn pada maa jẹ dandan fun un, ti o ba mọ́ ṣiwaju ki oòrùn to yọ pẹlu odiwọn rakah kan, sisan irun alufajari pada maa jẹ dandan fun un Ti o ba mọ ṣiwaju

wiwọ oòrùn pẹlu odiwọn rakah kan, sisan irun Asr pada maa di dandan fun un Ti o ba mọ ṣiwaju idaji oru pẹlu odiwọn rakah kan, sisan irun Ishai jẹ dandan fun un, Ti o ba mọ lẹyin idaji oru, irun Ishai ko jẹ dandan fun un, o maa ki irun alufajari ti asiko rẹ ba tó. Ọlọhun- mimọ ni fun Un ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

﴿فَإِذَا قَضَيْتُمُ ٱلصَّلَوٰةَ فَٱذْكُرُوا۟ ٱللَّهَ قِيَٰمًا وَ قُعُودًا وَعَلَىٰ جُنُوبِكُمْ ۚ فَإِذَا ٱطْمَأْنَنتُمْ فَأَقِيمُوا۟ ٱلصَّلَوٰةَ ۚ إِنَّ ٱلصَّلَوٰةَ كَانَتْ عَلَى ٱلْمُؤْمِنِينَ كِتَٰبًا مَّوْقُوتًا ﴿١٠٣﴾﴾[النساء: 103]

{Nígbà tí ẹ bá sì fọkàn balẹ̀ (ìyẹn nígbà tí ẹ bá wọnú ìlú), kí ẹ kírun (ní pípé). Dájúdájú ìrun kíkí jẹ́ ọ̀ran-anyàn tí A fi àkókò sí fún àwọn onígbàgbọ́ òdodo}[Surah An-Nisâ': 103] O n túmọ̀ si: Ọran-anyan kan ti a fi akoko kan pato si i, ko lẹtọọ fun ọmọniyan lati mu irun jade kuro ni akoko rẹ, tabi ki o bẹ̀rẹ̀ rẹ ṣiwaju akoko rẹ

Ibeere kejilelọgbọn: Mo ri nǹkan oṣù mi lori irun? Ki ni maa ṣe? Njẹ maa san irun ti o jẹ ni asiko nnkan oṣu pada bí?

Idahun kejilelọgbọn: Ti nnkan oṣu ba ṣẹlẹ lẹyin wiwọle akoko irun- bii ki o ri nnkan oṣu lẹyin ti oorun bá yẹ àtàrí pẹlu ọgbọn iṣẹju fun apẹrẹ- lẹyin ti o ba mọra kuro nibi

nnkan oṣu yoo san irun yii pada, eyi ti akoko rẹ wọle nigba ti o jẹ ẹni ti o mọ Fun ọrọ Ọba ti ọla Rẹ ga ti O sọ pe:

﴿... إِنَّ ٱلصَّلَوٰةَ كَانَتۡ عَلَى ٱلۡمُؤۡمِنِينَ كِتَٰبٗا مَّوۡقُوتٗا ١٠٣﴾[النساء: 103]

{Dájúdájú ìrun kíkí jẹ́ ọ̀ran-anyàn tí A fi àkókò sí fún àwọn onígbàgbọ́ òdodo}[Surah An-Nisâ': 103] Ko nii san irun ti o jẹ ni akoko nnkan oṣu pada; fun ọrọ rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ninu hadisi ti o gun: "Ṣe kii ṣe pe ti o ba ṣe nnkan oṣu ko nii kirun, ko si nii gba awẹ ni". Awọn onimimọ fi ẹnu ko lori pe dajudaju ko nii san irun ti o jẹ ni asiko nnkan oṣu pada Ṣugbọn ti o ba mọ, ti nnkan ti o ṣẹku ninu akoko jẹ odiwọn rakah ati ju bẹẹ lọ, yoo kirun ni asiko yẹn ti o mọ nibẹ; fun ọrọ rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe: "Ẹni ti o ba ba rakah kan ninu Asr ṣiwaju ki oorun to wọ, o ti ba Asr" Ti o ba mọ́ ni akoko Asr, tabi ṣiwaju yiyọ oorun, ti nnkan ti o ṣẹku ti oorun fi maa wọ̀ tàbí yọ jẹ odiwọn rakah kan, yoo ki Asr nibi ọ̀rọ̀ akọkọ, yoo si ki Alufajari nibi ọ̀rọ̀ keji

Ibeere kẹtalelọgbọn: Ìyá mi to ọmọ ọdun marundinlaadọrin, ko si bímọ lati bii ọdun mọkandinlogun, ni báyìí, ẹjẹ n da gan lara rẹ lati bii ọdún mẹ́ta, o da bii pe àìsàn ni ti o ṣe e ni àsìkò yẹn, awẹ si ni o n bọ̀ yii, ìmọ̀ràn wo ni ẹ maa gba a? Ki ni iru rẹ maa ṣe?

Idahun kẹtalelọgbọn: Ìdájọ́ irú obìnrin ti ẹjẹ ti o pọ gan n jáde lara rẹ yii ni: Ki o gbe irun ju silẹ ati awẹ ni asiko iṣesi rẹ ṣiwaju iṣẹlẹ ti o ṣẹlẹ si i yii, ti o ba jẹ pe iṣesi rẹ ni pe o maa n ṣe nnkan oṣu ni ibẹrẹ gbogbo oṣu fun ọjọ mẹfa fun apẹrẹ, yoo ko ara ro lati ibẹrẹ gbogbo oṣu fun ọjọ mẹfa ti ko nii kirun tabi gba awẹ, ti o ba ti pari yoo wẹ yoo si kirun yoo si gba awẹ

Bi obìnrin yii yoo ṣe maa kirun ati awọn iru rẹ ni pe: Yoo fọ gbogbo ojú ara rẹ dáadáa, yoo wàá wé nǹkan mọ ọn, yoo si ṣe aluwala, yoo maa ṣe ìyẹn lẹyin wiwọle irun ọran-anyan, gẹgẹ bẹẹ naa ni yoo ṣe maa ṣe e ti o ba fẹ yan nafila ni igba ti o yatọ si awọn akoko awọn irun ọran-anyan

Ni iṣesi yii- nitori inira ti o wa fun un- o lẹtọọ fun un lati da irun Zuhr ati Asr papọ, ati irun Magrib ati Ishai; titi ti iṣẹ rẹ yii o fi jẹ ẹyọkan fun irun meji: Irun Zuhr ati Asr Ẹyọkan fun meji: Irun Magrib ati Ishai. Ẹyọkan fun irun Alufajari naa, yoo waa ṣe e ni ẹẹmẹta rọ́pò ki o jẹ ẹẹmarun-un. Maa tun un wí ni ẹẹkan sii pe: Ti o ba ti fẹ mọra yoo fọ oju ara rẹ, yoo si wé aṣọ tabi nnkan ti o jọ ọ mọ ọn tító ti nnkan ti o n jade yoo fi fuyẹ, lẹyin naa yoo ṣe aluwala, yoo ki Zuhr ni mẹrin, ati Asr ni mẹrin, Magrib ni mẹta, Ishai ni mẹrin, ati alufajari ni rakah meji, eyi n túmọ̀ si pe: ko nii din irun ku, gẹgẹ bi àwọn èèyàn kan ṣe n lero. Ṣugbọn o lẹtọọ fun un

lati da irun Zuhr ati Asr papọ, ati Magrib ati Ishai papọ, ninu ki o da Zuhr ati Asr papọ ni ti lílọ́ lára tabi títì si iwájú, gẹgẹ bẹẹ naa ni Magrib pẹlu Ishai ninu ti lílọ́ lara tabi títì si iwájú, ti o ba fẹ ṣe nafila pẹlu aluwala yii ko si ohun ti o burú nibẹ.

Ibeere kẹrinlelọgbọn: Ki ni idajọ kí obinrin wà ni mọsalasi ọwọ ti o si jẹ ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu; fun titẹti si awọn hadisi ati awọn khutubah?

Idahun kẹrinlelọgbọn: Ko lẹtọọ fun obinrin ti o n ṣe nnkan oṣu lati wa ninu mọsalasi eewọ tabi mọsalasi mìíràn , ṣugbọn o lẹtọọ fun un lati kọja ninu mọsalasi lati mu nnkan ti o ni bukaata si nibẹ ati nnkan ti o jọ iyẹn Gẹgẹ bi Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣe sọ fun Aisha nigba ti o pa a laṣẹ mu khumroh wa[1], o sọ pe: O wa ninu mọsalasi, mo si n ṣe nnkan oṣu. O sọ pe: “Dajudaju nnkan oṣu rẹ ko si ni ọwọ rẹ”. Ti ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu ba kọja ninu mọsalasi, ti ọkàn rẹ si balẹ̀ pe ẹ̀jẹ̀ ko nii kan sínú mọsalasi, ko si ẹṣẹ fun un.

Ṣugbọn ti o ba fẹ wọle ki o jokoo, eleyii ko lẹtọọ

---

[1] Al-Khumroh: Oun ni itẹ ti olukirun maa n fi ori kanlẹ lori rẹ, wọn sọ ọ ni khumroh; nitori pe o maa n khammaroh oju, itumọ rẹ ni pe: O maa n bo o

Ẹri lori iyẹn ni pe: Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pa awọn obinrin laṣẹ nibi irun yidi lati jade lọ si aaye ti wọn ti n ki irun yidi (àwọn ọdọbinrin ti wọn ṣẹṣẹ bàlágà, ati awọn obìnrin ti wọn maa n wà nínú ilé lẹ́yìn gàgá, ati awọn ti n ri ẹjẹ nkan oṣù), ṣùgbọ́n wọn pa àṣẹ fun awọn ti n ṣe nnkan oṣu lati jìnnà si ààyè ìkírun. Ìyẹn n tọka si pe ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu ko lẹtọọ fun un lati wa nínú mọsalasi lati tẹti si khutuba, tabi ẹkọ ati awọn hadisi

*

## Ninu awọn idajọ imọra nibi irun

Ibeere karundinlogoji: Njẹ nnkan ti o n san ti o n jade lára obìnrin- funfun ni o jẹ ni tabi pupa- jẹ nnkan ti o mọ àbí nnkan ẹgbin ni bí? Njẹ aluwala jẹ dandan nibẹ, pẹlu nini imọ pe o n jade lai dúró? Ki ni idajo ti o ba n ṣe ṣegeṣege, pataki julọ ọpọlọpọ awọn obinrin- paapaa julọ awọn akẹ́kọ̀ọ́ lobinrin- wọn maa n ka iyẹn si ìtutù abẹ́ ti adamọ, ti aluwala ko jẹ dandan latara rẹ?

Idahun karundinlogoji: Eyi ti o han si mi lẹyin iwadii ni pe: Nǹkan ti o n san ti o n jade lára obinrin ti ko ba jade lati inú àpò ìtọ̀, bi ko ṣe pe o n jade láti apo ibi, nnkan ti o mọ ni, ṣugbọn yoo ba aluwala jẹ tòun ti bi o ṣe jẹ nnkan ti o mọ; nitori pe wọn ko ṣe ni majẹmu fun nnkan ti o n ba aluwala jẹ lati jẹ nnkan ẹgbin, gẹ́gẹ́ bíi iso ti o n jade lati idi, ko ni ara, tòun ti bẹẹ naa o n ba aluwala jẹ.

Lori eyi, ti o ba jade lara obìnrin ti o si ni aluwala, yoo ba aluwala jẹ, o si di dandan fún un ki o tun un ṣe.

Ti ko ba dúró, ko nii ba aluwala jẹ, ṣugbọn yoo maa ṣe aluwala fun irun ti akoko rẹ ba wọle, ti yoo si kirun ọran-anyan ati naafila ni akoko ti o ṣe aluwala nibẹ yii, yoo ka Kuraani, yoo si ṣe nnkan ti o fẹ ninu nnkan ti wọn ṣe ni ẹtọ fun un Gẹgẹ bi awọn onimimọ ṣe sọ nipa eyi nibi ẹni ti n tọ̀

sára, eleyii ni idajọ nnkan ti o n sàn ni abala imọra, nnkan ti o mọ ni, ni abala biba aluwala jẹ, o jẹ nnkan ti o n ba aluwala jẹ ayafi ti ko ba dúró, ti ko ba duro ko nii ba aluwala jẹ, ṣugbọn o jẹ dandan fun obinrin naa lati má ṣe aluwala fun irun afi lẹyin ti akoko rẹ ba wọle, ki o si wé nǹkan mọ ọn.

Ṣugbọn ti o ba maa n dá, ti o si wa ninu iṣesi rẹ lati maa dá ni awọn akoko irun, yoo lọ irun lara di asiko ti o maa n dá nibẹ, niwọn igba ti ko ba paya ki akoko irun lọ, ti o ba paya rẹ yoo ṣe aluwala, yoo si wé aṣọ mọ ọn, yoo si kirun

Ko wa si iyatọ laaarin eyi ti o kere ati eyi ti o pọ; nitori pe oju ara ni gbogbo ẹ ti n jáde, kekere rẹ ati pupọ rẹ maa jẹ nnkan ti o n ba aluwala jẹ, yatọ si eyi ti o n jade lati ẹ̀yà ara ti o ṣẹku gẹgẹ bii ẹjẹ ati eebi, ko nii ba aluwala jẹ, ati kekere rẹ ni o tabi pupọ rẹ

Ṣugbọn ini adisọkan awọn obinrin kan pe ko lee ba aluwala jẹ, eleyii mi ko mọ ẹri kankan fun un, afi ọrọ kan ti Ibn Hazmi- ki Ọlọhun kẹ ẹ- sọ pe: Dajudaju eyi ko lee ba aluwala jẹ. Ṣugbọn ko sọ ẹri kankan fun eyi, ti o ba ni ẹri kan ninu iwe Ọlọhun ati ọrọ Ojiṣẹ Ọlọhun tabi awọn ọrọ awọn sọhaba ni, ko ba jẹ awijare

O jẹ dandan fun obinrin lati bẹru Ọlọhun, ki o si ko akolekan imọra rẹ; nitori pe irun, wọn ko lee tẹwọ gba a

laisi imọra ko da ki o kirun ni ìgbà ọgọrun-un, bi ko ṣe pe apakan awọn onimimọ sọ pe: Dajudaju ẹni ti o n kirun laini imọra maa di keferi; nitori pe eyi wa ninu abala iṣe yẹyẹ pẹlu awọn aayah Ọlọhun- mimọ ni fun Un ti ọla Rẹ ga-

Ibeere kẹrindinlogoji: Ti obìnrin ti nnkan ti n san n jade lara rẹ lai dúró fun irun ọran-anyan, njẹ o tọna fun un lati ki nnkan ti o ba fẹ ninu awọn nafila tabi ki o ka Kuraani pẹlu aluwala ọran-anyan yẹn titi di akoko ọran-anyan keji?

Idahun kẹrindinlogoji: Ti o ba ṣe aluwala fun irun ọran-anyan lati ìbẹ̀rẹ̀ akoko, o lẹ́tọ̀ọ́ fun un lati ki nnkan ti o fẹ ninu awọn ọran-anyan ati awọn nafila ati kika Kuraani titi ti akoko irun miiran yoo fi wọle

Ibeere kẹtadinlogoji: Njẹ o tọna fun obinrin yẹn lati ki irun duha pẹlu aluwala alufajari?

Idahun kẹtadinlogoji: Iyẹn ko tọna; nitori pe irun duha jẹ nnkan ti o ni akoko, o jẹ dandan ki o ṣe aluwala fun un lẹyin wiwọle akoko rẹ; nitori pe eleyii da gẹgẹ bii ẹni ti ẹjẹ awaada n da lara rẹ, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- si ti pa ẹni ti ẹjẹ awaada n da lara rẹ laṣẹ lati maa ṣe aluwala fun gbogbo irun kọ̀ọ̀kan

Akoko Zuhr ni: Lati igba ti orun ba ti yẹ atari titi di akoko Asr

Akoko Asr: Lati igba ti akoko Zuhr ba ti lọ titi di akoko ti oorun maa di aláwọ̀ ìyeyè, ati pe akoko làlúrí rẹ ni titi di wiwọ oòrùn.

Akoko Magrib: Lati akoko wiwọ oòrùn titi ti awonpapa pupa yóò fi wọlé.

Akoko Ishai: Lati wiwọle awonpapa pupa titi di idaji oru

Ibeere kejidinlogoji: Njẹ o tọna fun obinrin yii lati ki irun oru ti idaji oru ba pari pẹlu aluwala Ishai?

Idahun kejidinlogoji: Rara, ti idaji oru ba pari, o jẹ dandan fun un lati tun aluwala ṣe, àwọn kan sọ pe: Ko jẹ dandan fun un lati tun aluwala ṣe. Oun ni eyi ti o tẹsuwọn julọ

Ibeere kọkandinlogoji: Ki ni ipari akoko irun Ishai? Ati pe bawo ni dida a mọ ṣe maa rọrun?

Idahun kọkandinlogoji: Ipari akoko Ishai ni idaji oru, wọn maa da iyẹn mọ pẹlu dida nnkan ti o wa laaarin wiwọ oòrùn ati yiyọ alufajari si meji, idaji akọkọ ni akoko Ishai maa pari pẹlu rẹ, ti idaji oru keji maa ṣẹku ti ko kii ṣe akoko kankan, bi ko ṣe pe gaga ni laaarin Ishai ati alufajari

Ibeere ogoji: Ti ẹni ti nnkan ti o n san jáde kelekele yẹn ba ṣe aluwala, ti o tun wa jáde lẹẹkan sii lẹ́yìn tí ó ti ṣe

aluwala tan șiwaju ki o to kirun, ki ni o jẹ dandan fun un lati ṣe?

Idahun ogoji: Ti o ba maa n ṣe ṣegeṣege, ki o ṣe sùúrù titi ti akoko ti o maa n dá nibẹ fi maa wọlé, ṣugbọn ti ko ba si iṣesi kan ti o han fun un, igba mii yoo jade, igba mii ko nii jade, nigba naa yoo maa ṣe aluwala lẹyin wiwọle akoko irun, yoo si kirun, ti nnkankan ko si jẹ dandan fun un lati ṣe.

Ibeere kọkanlelogoji: Ki ni o jẹ dandan fun ẹni ti nnkan ti o sàn yẹn da si ni ara tabi aṣọ lati ṣe?

Idahun kọkanlelogoji: Ti o ba jẹ nnkan ti o mọ, nnkankan ko jẹ dandan fun un, ti o ba jẹ nnkan ẹgbin- ti o n jade lati inu apo itọ- o di dandan fun un lati fọ ọ

Ibeere kejilelogoji: Nipa ṣíṣe aluwala latara nnkan ti o n sàn yẹn, njẹ fifọ awọn orikee aluwala nikan to bí?

Idahun kejilelogoji: Bẹẹni, ìyẹn ti to ti o ba jẹ nnkan ti o mọ, oun ni eyi ti o n jade lati inu apo ìbímọ, ti ko kii ṣe lati inu apo itọ

Ibeere kẹtalelogoji: Ki ni idi ti wọn ko fi gba hadisi kankan ti o da lori bibajẹ aluwala pẹlu nnkan ti o n san yẹn wá láti ọdọ Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba

a- tòun ti bi o ṣe jẹ pe awọn sọhaba lobinrin maa n ṣe ojúkòkòrò láti béèrè nipa idajọ awọn alamọri ẹsin wọn?

Idahun kẹtalelogoji: Nitori pe nnkan ti o n sàn yẹn kii ṣe gbogbo obìnrin ni o maa n ṣẹlẹ si.

Ibeere kẹrinlelogoji: Ẹni ti ko ba kii ṣe aluwala ninu awọn obinrin; latari aimọkan rẹ nipa idajọ naa, ki ni o jẹ dandan fun un lati ṣe?

Idahun kẹrinlelogoji: O jẹ dandan fun un lati ronupiwada lọ si ọdọ Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn-, ki o si beere nipa ìyẹn lọdọ awọn onimimọ

Ibeere karundinlaadọta: Awọn kan maa n sọ pe ẹ sọ pe ki èèyàn má ṣe aluwala latara nnkan ti n sàn naa?

Idahun karundinlaadọta: Iró ni ẹni tí n fi ọrọ yii ti si mi lọ́dọ̀ ń pa, eyi ti o han ni pe o gbọye nínú ọrọ mi pe: "Dajudaju o jẹ nnkan ti o mọ", wi pe ko nii ba aluwala jẹ

Ibeere kẹrindinlaadọta: Ki ni idajọ nǹkan ti o fẹ́ dudu ti o maa n jade latara obinrin ṣiwaju nnkan oṣu pẹ̀lú ọjọ kan tabi ju bẹẹ lọ tabi ti o kere si i, ti o ṣe pe nnkan ti o n jade da bíi owu tiirin dudu kan, tabi aláwọ̀ ilẹ̀ tabi nnkan ti o jọ iyẹn? Ki ni idajọ ti o ba jẹ lẹ́yìn nnkan oṣu?

Idahun kẹrindinlaadọta: Ti eyi ba wa ninu awọn nǹkan ti maa n ṣáájú nnkan oṣu, a jẹ wipe nnkan oṣu ni, wọn maa

da iyẹn mọ pẹlu awọn irora ati inu rirun ti o maa n sáábà ṣẹlẹ̀ si ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu

Ṣugbọn omi ti o fẹ dudu lẹyin nnkan oṣu, yoo ṣe suuru titi ti yoo fi lọ; nitori pe dudu ti o so pọ mọ nnkan oṣu, nnkan oṣu ni; fun ọrọ Aisha- ki Ọlọhun yọnu si i- pe: Ma kanju titi ti o fi maa ri omi funfun. Ọlọhun ni O ni imọ julọ

*

## Ninu awọn idajọ nnkan oșu ni Hajj ati Umrah

Ibeere kẹtadinlaadọta: Bawo ni ẹni ti o n șe nnkan oșu șe maa ki rakah meji gbigbe urumi? Njẹ o ni ẹtọ fun obinrin ti o n șe nnkan oșu lati paara èyíkéyìí aaya Kuraani ni jẹ́jẹ́, àbí ko ni ẹtọ?

Idahun kẹtadinlaadọta: Akọkọ: O tọ ki a mọ pe gbigbe urumi ko ni irun kankan ti o n bẹ fun un; dajudaju ko wa lati ọdọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe o șe irun kan ni ofin fun ìjọ rẹ fun gbigbe urumi, boya pẹlu ọrọ rẹ ni tabi pẹlu ișe rẹ tabi pẹlu ifirinlẹ rẹ Ikeji: Dajudaju obinrin yii ti o ri nnkan oșu șiwaju ki o to gbe urumi, ọ rọrun fun un lati gbe urumi ti o si n șe nnkan oșu ; Nitori pe Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pa Asmau ọmọ Umays, iyawo Abu Bakr- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- lașẹ nigba ti ẹjẹ ìbímọ n da lara rẹ ni Zhul Hulayfah, o pa a lașẹ lati wẹ ki o si de așọ kan mọ oju ara rẹ, ki o si gbe urumi, gẹgẹ bẹẹ naa ni ẹni ti o n șe nnkan oșu naa, yoo wa lori urumi rẹ titi yoo fi mọ, lẹyin naa yoo rọkirika ile Oluwa, yoo si sa sàfá ati máríwà.

Șugbọn ibeere ti o béèrè pé: Njẹ o ni ẹtọ fun un lati ka Kuraani? Bẹẹni, ẹni ti o n șe nnkan oșu ni ẹtọ lati ka

Kuraani nigba bukaata tabi anfaani, ṣugbọn laini bukaata tabi anfaani, bi ko ṣe pe o fẹ ka a ni ti ijọsin ati isunmọ Ọlọhun, eyi ti o daa julọ ni ki o ma ka a

Ibeere kejidinlaadọta: Obinrin kan ṣe irin ajo lọ si Hajj, ni o wa ri nǹkan oṣù rẹ lati ọjọ karùn-ún ti o ti bẹ̀rẹ̀ irin ajo rẹ, lẹyin dide rẹ si awọn aaye ti wọn ti maa n gbe áràmí, o wẹ, o si gbe arami, ti ko si tii mọra nibi nǹkan oṣù re, igba ti o de Mẹka Alapọn-ọnle, o wa ni ita Haram, ko si ṣe nnkankan ninu awọn iṣẹ Hajj tabi Umrah, o wa ni Mina fun ọjọ meji, lẹyin naa o mọra, o si wẹ, o si pe gbogbo iṣẹ Umrah ti o si jẹ ẹni ti o mọ, lẹyin naa ẹjẹ naa pada nigba ti o n ṣe Tawaaful Ifaadah, ṣùgbọ́n ojú n tì í, o si pari awọn iṣẹ Hajj, ti ko sọ fun alaṣẹ rẹ afi lẹyin dide rẹ pada si ilu rẹ, ki ni idajọ iyẹn? Idahun kejidinlaadọta: Idajọ nibi eyi ni pe: Dajudaju ẹjẹ ti o ṣẹlẹ si i nibi Tawaaful Ifaadoh, ti o ba jẹ pe ẹjẹ nnkan oṣu ni, eyi ti o da a mọ pẹlu adamọ rẹ tabi awọn irora, dajudaju Tawaaful Ifaadoh naa ko ni alaafia, o si jẹ dandan fun un lati pada si Makkah; lati ṣe Tawaaful Ifaadoh, ti yoo si gbe arami Umrah lati awọn aaye ti wọn ti maa n gbe e, yoo si ṣe Umrah pẹlu irọkirika ile Oluwa ati sisa safa ati mariwa, yoo si ge irun rẹ, lẹyin naa yoo ṣe Tawaaful Ifaadoh.

Ṣugbọn ti ẹjẹ naa ko ba kii ṣe ẹjẹ nnkan oṣu, ẹjẹ ti adamọ ti a mọ, bi ko ṣe pe o jade latara àpọ̀jù àwọn èèyàn

tabi ibẹru, tabi nnkan ti o jọ iyẹn, dajudaju irọkirika rẹ ni alaafia lọdọ ẹni ti ko fi imọra ṣe majẹmu fun irọkirika ile Oluwa

Ti pípadà ko ba rọrun fun un nibi ọ̀rọ̀ akọkọ, bóyá o wa ni ilu ti o jinna, Hajj rẹ ni alaafia; nitori pe ko ni ikapa ju nnkan ti o ṣe lọ

Ibeere kọkandinlaadọta: Obinrin kan de ni ẹni ti o gbe áràmí Umrah, lẹyin dide rẹ si Makkah ni o ba ri nnkan oṣu, eleewọ rẹ si gbọdọ̀ ṣe ìrìn-àjò ni kiakia, ti ko si ni ẹni kankan ni Makkah, ki ni idajọ naa?

Idahun kọkandinlaadọta: Yoo ṣe ìrìn-àjò pẹlu rẹ, ti yoo si wa lori arami rẹ, lẹyin naa yoo ṣeri pada ti o ba ti mọ, eyi o maa ri bẹ́ẹ̀ ti o ba wa ni Saudi; nitori pe ṣiṣẹri pada rọrun, ko si bukaata si idamu kankan, tabi si ìwé ìrìnnà ati nnkan ti o jọ ọ.

Ṣugbọn ti o ba jẹ ajoji, ti ṣiṣẹri pada nira fun un, yoo wé nǹkan mọ́ ojú ara rẹ, yoo si rọkirika ile Oluwa, yoo sa safa ati mariwa, yoo ge irun rẹ, yoo si pari Umrah rẹ ni ìrìn-àjò kan naa, nitori pe irọkirika ile Oluwa rẹ nigba naa ti di kò-ṣeé-má-ṣe, kò-ṣeé-má-ṣe si maa n sọ nnkan eewọ di ẹtọ ni.

Ibeere aadọta: Ki ni idajọ Musulumi-binrin ti o ṣe nnkan oṣu ni awọn ọjọ Hajj rẹ, njẹ hajj yẹn to fun un? Idahun

aadọta: Eyi ko ṣee dahun si titi ti a fi maa mọ igba ti o ṣe nnkan oṣu? Iyẹn ri bẹ́ẹ̀ nitori pe awọn iṣẹ Hajj kan n bẹ ti nnkan oṣu ko lee ni ki èèyàn má ṣe wọn, àwọn iṣẹ́ kan naa si wa ti nǹkan oṣù ko nii jẹ ki a le ṣe wọn, gẹgẹ bii irọkirika ile Oluwa, ko rọrun lati rọkirika rẹ afi ki o jẹ ẹni ti o mọ, ṣùgbọ́n o rọrun lati ṣe àwọn iṣẹ́ hajj ti o yatọ si i pẹ̀lú nǹkan oṣù.

Ibeere kọkanlelaadọta: Mo ti ṣe hajj ni ọdún ti o kọjá, mo si pe gbogbo awọn iṣẹ hajj yatọ si tawaaful ifaadoh ati tawaafu idagbere, nigba ti o ṣe pe àwíjàre ti o ba sharia mu ni ko jẹ ki n le ṣe mejeeji, mo wa ṣeri pada si ile mi ni Mọdina lori pe ki n pada ni ọjọ mìíràn; lati lọ ṣe tawaaful ifaadoh ati ti idagbere, ṣùgbọ́n pẹ̀lú aimọkan mi nípa awọn alamọri ẹsin, mo bọ́ra kúrò nibi gbogbo nnkan, mo ṣe gbogbo nnkan ti wọn ṣe ni eewọ nínú áràmí, mo wa beere nipa ṣiṣẹri pada mi lati rọkirika ile Oluwa, wọn sọ fun mi pe: Ko tọ fun ẹ lati rọkirika ile Oluwa, o ti ba hajj jẹ, titun un ṣe si jẹ dandan fun ẹ ni ọdun ti o n bọ, pẹ̀lú didu maalu tabi abo rakunmi, njẹ eyi tọna? Njẹ ọ̀nà àbáyọ mii wa? Ki ni nnkan náà? Njẹ Hajj mi ti bajẹ? Njẹ dida pada rẹ jẹ dandan fun mi? Ẹ ṣe mi ni anfaani pẹlu nnkan ti maa ṣe, Ọlọhun a bukun yin

Idahun kọkanlelaadọta: Eyi naa wa ninu awọn adanwo ti o n ṣẹlẹ ninu ṣíṣe alaye idajọ laini imọ, iwọ ti o wa ninu

iṣesi yii, o jẹ dandan fun ẹ lati ṣeri pada si Makkah lati lọ ṣe tawaaful ifaadoh nikan. Ṣugbọn nípa irọkirika ile Oluwa ti idagbere, ko jẹ dandan fun ẹ, ni iwọn igba ti o ba si jẹ ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu nigba ti o jáde kuro ni Makkah, iyẹn ri bẹ́ẹ̀ nitori pe ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu, irọkirika ile Oluwa ti idagbere ko jẹ dandan fun un Fun hadisi Ibnu Abbas- ki Ọlọhun yọnu si wọn-: Wọn pa awọn eniyan láṣẹ lati jẹ ki igbẹyin iṣẹ́ hajj wọn jẹ irọkirika ile Oluwa, ṣùgbọ́n wọn ṣe e ni fifuyẹ fun ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu Ninu ẹgbawa ti Abu Daud: Ki igbẹyin iṣẹ́ ti wọn a ṣe ni ilé Olúwa jẹ irọkirika ile naa. Nitori pe Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- nigba ti wọn fun un ni iro nipa pe Sofiyyah ṣe tawaaful ifaadoh, o sọ pe: "Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, ki o yaa maa lọ". Eyi da lori pe irọkirika ile Oluwa ti idagbere ko nii jẹ dandan fun ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu. Ṣugbọn irọkirika ile Oluwa ti ifaadọ, o jẹ dandan fun ẹ, nigba ti o ti wa bọra kuro nibi gbogbo nnkan ni ẹni ti o ṣe aimọkan pẹlu rẹ, dajudaju eyi ko ko inira ba ẹ; nitori pe alaimọkan ti o ṣe nnkankan ninu awọn eewọ gbigbe arami, ko si nǹkan kan fun un; Fun ọrọ Ọba ti ọla Rẹ ga pe:

﴿... رَبَّنَا لَا تُؤَاخِذْنَآ إِن نَّسِينَآ أَوْ أَخْطَأْنَا ...﴾[البقرة: 286]

{Olúwa wa, má ṣe mú wa tí a bá gbàgbéra tàbí (tí) a bá ṣàṣìṣe}[Surah Al-Baqarah: 286] Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe: “Mo ti ṣe e”. Ati ọrọ Rẹ pe:

﴿...لَيۡسَ عَلَيۡكُمۡ جُنَاحٞ فِيمَآ أَخۡطَأۡتُم بِهِۦ وَلَٰكِن مَّا تَعَمَّدَتۡ قُلُوبُكُمۡۚ...﴾[الأحزاب: 5]

{Kò sí ẹ̀ṣẹ̀ fun yín nípa ohun tí ẹ bá ṣàṣìṣe rẹ̀, ṣùgbọ́n (ẹ̀ṣẹ̀ wà níbi) ohun tí ọkàn yín mọ̀ọ́mọ̀ ṣe}[Surah Al-Ahzâb: 5] Gbogbo nnkan eewọ ti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- kọ wọn fun ẹni ti o gbe arami, ti o ba ṣe e ni ti aimọkan tabi ni ẹni ti o gbagbe, tabi ni ẹni ti wọn jẹnípá, ko si ẹṣẹ kankan fun un, ṣugbọn gbogbo igba ti awijare rẹ ba ti kúrò, o jẹ dandan fun un lati jáwọ́ kuro nibi nnkan eewọ naa.

Ibeere kejilelaadọta: Obinrin ti o ẹjẹ ibimọ n da lara rẹ, ti ẹjẹ ibimọ rẹ ba bẹrẹ ni ọjọ kẹjọ ninu oṣu Dhul-Hijjah, ti o ti pari awọn origun Hajj yatọ si irọkirika ile Oluwa ati sisa safa ati mariwa, ṣùgbọ́n o ṣe akiyesi pe oun ti kọ́kọ́ mọ́ lẹyin ọjọ mẹwaa, njẹ yoo mọra, ti yoo wẹ, ti yoo si pe origun ti o ṣẹku ti o jẹ pe oun ni irọkirika ile Oluwa ti Hajj?

Idahun kejilelaadọta: Ko lẹtọọ fun un lati wẹ ati lati rọkirika ile Oluwa titi ti mimọ yoo fi da a loju, nnkan ti a n gbọye ninu ibeere naa nigba ti o sọ pe: “Kọ́kọ́” ni pe ko ri mimọ ni pipe, dandan si ni ki o ri mimọ ni pepe, igbakigba

ti o ba mọ́ ni yoo wẹ, yoo si ṣe tawaafu ati safa ati mariwa naa.

Ti o ba sá sàfá àti máríwà ṣiwaju irọkirika ile Oluwa, ko burú; nitori pe Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wọn bi i leere ni Hajj nipa ẹni ti o sa safa ati mariwa ṣiwaju ki o to rọkirika ile Oluwa, o sọ pe: "Kò burú"

Ibeere kẹtalelaadọta: Obinrin kan gbe arami Hajj lati ààyè kan ti a n pe ni "Sael" ni ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu, nigba ti o de Makkah, o lọ si Jeddah fun bukaata rẹ, o mọ ni Jeddah, o si wẹ, o si ya irun rẹ, lẹyin naa o ṣe Hajj rẹ ni aṣepe, njẹ Hajj rẹ ni alaafia? Njẹ nnkankan jẹ dandan fun un?

Idahun kẹtalelaadọta: Hajj rẹ ni alaafia, nnkankan ko jẹ dandan fun un

Ibeere kẹrinlelaadọta: Mo n lọ fun Umrah, mo wa kọja ni aaye ti wọn ti n gbe arami ti mọ si n ṣe nnkan oṣu, mi o wa gbe arami, mo wa wa ni Makkah titi ti mo fi mọ, mo wa gbe arami lati Makkah, njẹ eyi lẹtọọ? Tabi ki ni maa ṣe? Ki ni o jẹ dandan fun mi?

Ìdáhùn kẹrinlelaadọta: Iṣẹ yii ko lẹtọọ, ati pe obinrin ti o fẹ ṣe Umrah, ko lẹtọọ fún un ki o kọja aaye ti a ti ń gbe arami lai gbe arami, koda ki o jẹ ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu,

yoo gbe arami ni ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu, arami ti o gbe si maa ni àlàáfíà. Ẹri lori iyẹn ni pe: Asmau ọmọ Umays, iyawo Abu Bakr- ki Ọlọhun yọnu si wọn- bímọ, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- si ti lọ si Dhul Hulayfah ti o fẹ ṣe Hajj idagbere, o wa ranṣẹ si Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe: Bawo ni maa ṣe ṣe? O sọ pe: "Wẹ̀, ki o si wé oju ara rẹ pẹlu aṣọ kan, ki o si gbe arami". Ẹjẹ nnkan oṣu da gẹgẹ bii ẹjẹ ibimọ A maa sọ fun obinrin ti o n ṣe nnkan oṣu ti o ba kọja ni aaye ti a ti ń gbe arami, ti o si fẹ ṣe Umrah tabi Hajj, a maa sọ fún un pe: Wẹ, ki o si wé oju ara rẹ pẹlu aṣọ kan, ki o si gbe arami, Al-Istithfaar, itumọ rẹ ni pe: Yoo de aṣọ kan mọ oju ara rẹ, yoo si so o, lẹyin naa yoo gbe arami, boya pẹlu Hajj ni o tabi pẹlu Umrah, ṣugbọn ti o ba ti gbe arami wọ ti o si ti de Makkah, ko nii wa si ile Oluwa, ko si nii rọkirika rẹ titi ti yoo fi mọ Fun idi eyi, Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ fun Aisha nigba ti o ṣe nnkan oṣu ni asiko Hajj, o sọ fun un pe: "Ṣe nnkan ti alalaaji n ṣe, yatọ si ki o rọkirika ile Oluwa titi ti waa fi mọ", eleyii ni ẹgbawa Bukhari ati Muslim Ninu "Sọhiihu Bukhari" bákan náà, Aisha sọ pe nigba ti oun mọ, oun rọkirika ile Oluwa, oun si sa safa ati mariwa Eyi da lori pe ti obinrin ba gbe arami pẹlu Hajj tabi Umrah ti o si n ṣe nnkan oṣu, tabi nnkan oṣu de ba a ṣiwaju irọkirika ile Oluwa, dajudaju ko nii rọkirika ile Oluwa, ko si nii sa safa ati mariwa titi ti yoo fi mọ ti yoo si wẹ

Ṣugbọn ti o ba ti rọkirika ile Oluwa ti o si jẹ ẹni ti o mọ, lẹyin ti o wa pari irọkirika ni o wa ri nnkan oṣu, yoo tẹsiwaju, yoo si sa safa ati mariwa koda ki nnkan oṣu wa lara rẹ, yoo si ge ninu irun ori rẹ, yoo si pari Umrah rẹ; nitori pe wọn ko ṣe imọra ni majẹmu fun sisa safa ati mariwa.

Ibeere karundinlọgọta: Mo wa lati Yanbuh fun Umrah emi ati ìyàwó mi, ṣugbọn nigba ti mo de Jeddah, iyawo mi ri nnkan oṣu, ṣugbọn mo pari Umrah ni emi nikan yatọ si iyawo mi, ki ni idajọ nipa ti iyawo mi?

Idahun karundinlọgọta: Idajọ nipa iyawo rẹ ni pe: Yoo ṣe suuru titi ti yóò fi mọ, lẹyin yoo ṣe Umrah rẹ; Nitori pe Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- nigba ti Sofiyyah- ki Ọlọhun yọnu si i- ri nǹkan oṣù, o sọ pe: “Ṣe oun ni o maa da wa duro ni? Wọn sọ pe: O ti ṣe tawaaful ifaadọ. O sọ pe: “Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, ki o maa lọ” Ọrọ rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe: “Ṣe oun ni o maa da wa duro ni? Jẹ ẹri lori pe o jẹ dandan fun obinrin lati duro- ti o ba ri nnkan oṣu ṣiwaju tawaaful ifaadọ- titi ti yoo fi mọ, lẹyin naa yoo rọkirika ile Oluwa

Gẹgẹ bẹẹ naa ni irọkirika ile Oluwa ti Umrah, oun naa da gẹgẹ bii irọkirika ile Oluwa ti ifaadọ; nitori pe o jẹ origun kan ninu Umrah, ti ẹni ti o n ṣe Umrah ba ri nnkan

oṣu ṣiwaju irọkirika ile Oluwa, yoo ṣe suuru titi ti yoo fi mọ, lẹyin naa yoo rọkirika ile Oluwa

Ibeere kẹrindinlọgọta: Njẹ aaye ti a ti n sa safa ati mariwa wa lara Haram? Njẹ ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu maa sunmọ ọn? Njẹ o jẹ dandan fun ẹni ti o ba wọ Haram lati aaye ti a ti n sa safa ati mariwa lati yan nafila Tahiyyatul Masjid?

Idahun kẹrindinlọgọta: Eyi ti o han ni pe aaye ti a ti n sa safa ati mariwa ko si ninu mọsalasi; nitori idi eyi ni wọn fi mọ ogiri kan ti o ṣe opinya laaarin mejeeji, ṣugbọn ogiri kekere ni, ko si iyemeji pe oore ni fun awọn eniyan; nitori pe ti wọn ba mu u wọ inu mọsalasi ti wọn fi si ara rẹ, ì bá jẹ eewọ fun obinrin ti o ba ri nnkan oṣu laaarin irọkirika ile Oluwa ati sisa safa ati mariwa lati sa safa ati mariwa.

Ìdájọ́ ti maa ṣe ni pe: Ti o ba ri nnkan oṣu lẹyin irọkirika ile Oluwa ati ṣiwaju sisa safa ati mariwa, yoo sa safa ati mariwa; torí pé aaye ti a ti n sa safa ati mariwa kii ṣe ara mọsalasi.

Ṣugbọn nafila tahiyyatul masjid, a le sọ pe: Dajudaju ti ọmọniyan ba sa safa ati mariwa lẹyin irọkirika ile Oluwa, ti o wa pada si mọsalasi lẹ́yìn náà, yoo ki i, ti o ba si gbe nafila tahiyyatul masjid ju silẹ, ko si ẹṣẹ kankan fun un Eyi

ti o daa julọ ni ki o ṣe amulo anfaani naa, ki o si ki rakah meji; nitori ọla ti o n bẹ fun irun ni aaye yii.

Ibeere kẹtadinlọgọta: Mo ṣe Hajj, ni mo wa ri nǹkan oṣù, ojú wa n ti mi lati sọ fun èèyàn, mo wa wọ inu Haram, mo si kirun, mo si rọkirika ile Oluwa, mo tun sa safa ati mariwa, ki ni o jẹ dandan fun mi lati ṣe ti o si jẹ pe ẹyin ẹjẹ ìbímọ ni o wa

Idahun kẹtadinlọgọta: Ko lẹtọọ fun obinrin ti o ba n ṣe nnkan oṣu tabi ti ẹjẹ ibimọ ba n da lara rẹ lati kirun, boya ni Makkah ni tabi ni ilu rẹ tabi ni ibikíbi. Fun ọrọ Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti o sọ nipa obinrin pe: "Ṣe kii ṣe pe ti o ba ṣe nnkan oṣu ko nii kirun, ko si nii gba awẹ ni?". Àwọn Musulumi ti fi ẹnu ko lori pe ko lẹtọọ fun ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu lati gba awẹ, ko si lẹtọọ fun un lati kirun

O jẹ dandan fun obinrin yii ti o ṣe iyẹn, lati ronupiwada lọ si ọdọ Ọlọhun, ki o si wa aforijin nibi nnkan ti o waye lati ọwọ́ rẹ

Ṣugbọn irọkirika ile Oluwa rẹ ni asiko ti n ṣe nnkan oṣu ko ni alaafia, ṣugbọn sisa safa ati mariwa rẹ ni alaafia; nitori pe ọrọ ti o tẹsuwọn julọ ni pe a le sa safa ati mariwa ṣiwaju tawaafu ti hajj, lori eyi, o jẹ dandan fun un lati da irọkirika ile Oluwa pada; torí pe irọkirika ile Oluwa ti ifaadọ

jẹ origun kan ninu origun Hajj, ti a ko le bọra sílẹ̀ ni ti ikeji àyàfi pẹ̀lú rẹ.

Ti o ba ri bẹẹ, obinrin yii, ọkọ rẹ ko nii sunmọ ọn- ti o ba jẹ ẹni ti o ni ọkọ- titi ti yoo fi rọkirika ile Oluwa, wọn ko si nii ta kókó ìgbéyàwó rẹ- ti ko ba tii ni ọkọ- titi ti yoo fi rọkirika ile Oluwa, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- ni O ni imọ ju lọ

Ibeere kejidinlọgọta: Ti obinrin ba ri nnkan oṣu ni ọjọ Arafah, ki ni yoo ṣe?

Ìdáhùn kejidinlọgọta: Ti obinrin ba ri nnkan oṣu ni ọjọ, yoo tẹsiwaju nibi iṣẹ Hajj, yoo si ṣe nnkan ti awọn eniyan n ṣe, ko si nii rọkirika ile Oluwa titi ti yoo fi mọ́.

Ibeere kọkandinlọgọta: Ti obinrin ba ri nnkan oṣu lẹyin jiju oko jamratul akọba, ati ṣiwaju irọkirika ile Oluwa ti ifaadọ, ti oun ati ọkọ rẹ si so pọ mọ awọn arìnrìn-àjò kan ti wọn jọ n lọ papọ, ki ni o jẹ dandan fun un lati ṣe, ti o si mọ pe pipada ko lee rọrun fun oun lẹyin ìrìn-àjò rẹ?

Idahun kọkandinlọgọta: Ti pipada ko ba rọrun fun un, yoo we nǹkan mọ́ oju ara rẹ, lẹyin naa yoo rọkirika ile Oluwa fun làlúrí, ko si si ẹṣẹ kankan fun un, yoo si pari awọn iṣẹ hajj ti o ṣẹku

Ibeere ọgọta: Ti ẹni ti ẹjẹ ìbímọ ba n da lara rẹ ba mọ ṣiwaju ogoji ọjọ, njẹ hajj rẹ ni alaafia? Ti ko ba ri mimọ, ki ni yoo ṣe ti o si gbero ṣíṣe hajj?

Idahun ọgọta: Ti ẹni ti ẹjẹ ìbímọ ba n da lara rẹ ba mọ ṣiwaju ogoji ọjọ, yoo wẹ, yoo kirun, yoo si ṣe gbogbo nnkan ti awọn ti wọn mọ n ṣe, títí ti o fi dórí irọkirika ile Oluwa; nitori pe ẹjẹ ìbímọ ko si aala fun ọjọ ti o kere julọ fun un Ṣugbọn ti ko ba ri mimọ, dajudaju hajj rẹ ni alaafia, ṣugbọn ko nii rọkirika ile Oluwa titi ti yoo fi mọ Nitori pe Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- kọ fun ẹni ti o n ṣe nnkan oṣu kuro nibi irọkirika ile Oluwa, ati pe ẹjẹ ibimọ da gẹgẹ bii ẹjẹ nnkan oṣu nibi eyi

*

# Index

**Ibeere ọgọta nipa awọn idajọ ẹjẹ nnkan oṣu ati ibimọ** ........ 1

Ọrọ iṣaaju ........ 3

Ninu awọn idajọ ẹjẹ nnkan oṣu nibi irun ati awẹ ........ 5

Ninu awọn idajọ imọra nibi irun ........ 32

Ninu awọn idajọ nnkan oṣu ni Hajj ati Umrah ........ 39

# Get to know more about Islam

## in more than 100 languages

موسوعة الأحاديث النبوية
HadeethEnc.com

Accurate translations of Prophetic Hadiths and their explanations in more than (60) languages.

بيان الإسلام
byenah.com

Selected materials to introduce and teach Islam in more than (120) languages.

موسوعة القرآن الكريم
QuranEnc.com

Accurate translations of the meanings of the Quran in more than (75) languages.

موسوعات وخدمات إسلامية باللغات
s.islamenc.com

For more websites in world languages (s.islamcontent.com)

موسوعة المحتوى الإسلامي باللغات
islamcontent.com

Various and comprehensive Islamic materials in more than (125) languages.

ما لا يسع أطفال المسلمين جهله
kids.islamenc.com

Questions and answers for Muslim children and public in more than (40) languages.

جمعية خدمة المحتوى الإسلامي باللغات

جمعية الدعوة وتوعية الجاليات بالربوة



Yo138